**Lakaye Ọrọ**

ENITI o ba gba mi gbọ o gba Baba mi ti mbe l'orun gbọ. E o si mo otitọ, otitọ yio si sọ nyin di ominira.

# Irohin Yoruba

No. 817 | February 1—February 7, 1961 | KOBO MEJI (2D)




Jẹ egbogi ti o daraju fun ọmọde

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi

# MO FI ẸGBẸ OṢO ATI AJẸ SILẸ, NKO ṢE ẸGBẸ OKUNKUN MỌ

## 'Mo jare ẹjọ imulẹ awọn ajẹ, ọjọ iku mi ti yẹ'

**Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu kini ọdun yi ni omidan Lydia Ọlatundun, ọmọ Ọgbẹni Jacob Abọdunde Ile Oloonu, Oke Ṣọọṣi ni adugbo Oke-Ifa ni ilu Gbọngan wa si ọdọ Olotu Iwe "Irohin Yoruba," ẹniti o ṣe atọna rẹ wa ni Ẹni-Ọwọ Alufa S. O. Ọmọnubi " Doctor De Love " ti iṣe Alamojuto Ile Adura "African Independent Church" ni Shomolu iẹba Eko.**



Lydia Ọmọtundun si fi ẹnu ara rẹ jẹwọ fun Olotu Iwe "Irohin Yoruba" bi o ti ṣe di ọmọ ẹgbẹ awọn ajẹ ati gbogbo iwa apanijẹ ti o nhu pẹlu wọn nibẹ ati ohun ti o mu u fẹ fi ẹgbẹ okunkun na silẹ. Bayi ni Olotu ti ṣe mbere ọrọ lọwọ Ọmọtundun ti o si nfesi:—

OLOTU—Oruko rẹ?

ỌMỌ—Lydia Ọmọtundun.

OLOTU—Tani baba rẹ?

ỌMỌ—Jacob Abọdunde.

OLOTU—Tani iya rẹ?

ỌMỌ—Alice Ajisọla Abẹni

OLOTU—Nibo ni ilu nyin?

ỌMỌ—Ni ilu Gbọngan.

OLOTU—Ni adugbo ibo ni ni Gbọngan?

ỌMỌ—Ni Ile Oloonu, ni oke Ṣọọṣi.

OLOTU—Ọmọ ọdun melo ni ọ?

ỌMỌ—Ọmọ ọdun mejidinlogun.

OLOTU—Kini o ti rin ki o to gba ajẹ?

ỌMỌ—Iya mi agba ti mo ngbe ọdọ rẹ ni o pọ ajẹ si mi lẹnu, ti mo si fi di ajẹ lati igbana.

OLOTU—Ajẹ na ṣi ni ọ nisisiyi?

ỌMỌ—Oti o, nki iṣe ajẹ mọ, mo ti fi iṣẹ ati iṣe ajẹ silẹ mo ti kuro ninu ẹgbẹ okunkun, mo si ti di ọmọ Ẹgbẹ Aladura ti Ijọ "African Independent Church". Ṣomolu, labẹ alamojuto Ijọ na Ẹni-ọwọ Alufa S. O. Ọmọnubi.

OLOTU—Orukọ iya rẹ agba ti o gba ajẹ lọdọ rẹ?

ỌMỌ—Ọdẹwẹnu ni orukọ rẹ.

(Wo oju ewe kẹtala)

Aworan oke yi ni ti igbati Lydia Ọlatundun nfi ohun ija rẹ ti o fi nṣiṣẹ ajẹ han awọn oniwe irohin lẹhinti Alufa Ẹni-ọwọ S. O. Ọmọnubi "Doctor De Love", gbadura fun un tan.

* * *



Aworan ẹgbẹ yi ni ti igbati Alufa Ọmọnubi ngbadura gbigbona le ori Lydia ni ọjọ ti nwọn mu u wa fun iwosan inu hihọ (belly trouble).

## ỌRỌ OLOTU

### *A ko le mọ iya ọṣọ ju ọṣọ lọ, Ẹgbẹ Alakukọ ẹ jawọ ninu itanjẹ*

NI aipe yi ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ṣe ikede fun gbogbo awọn agbẹ-onikoko pe owo koko ti nwọn ti ngba ni ọgọjọ pọnun (£160) fun toọnu kan yio din si pọnun mejilelaadofa fun toọnu kan (£112) per ton nisisiyi. Gẹgẹbi iye ti Ijọba Ghana (Oke-Okun ti ngba koko tẹlẹ-tẹlẹ ri titi di isisiyi.

Ohun ti o si mu ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ti din owo koko ku ba ti Ghana dọgba ni pe, ifasẹnin owo koko ti wa pẹ lati ọdọ awọn oniṣowo koko agbaiye, sibẹsibẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria nfi ara da a ni, ṣugbọn nwọn ri i pe ti nwọn ba nfarada bẹ ẹ lọ, adanu nla ni yio jẹ fun gbogbo ilẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Nigbamiran ninu ẹsun-nawo ere ti nwọn ti nri lori koko ni nwọn ngba fun awọn iṣẹ idagbasoke ilu, ti nwọn fi nya awọn agbẹ lowo fi tọju oko, ti ṣe ọna-mọto kakiri arọko, fun idagbasoke iṣẹ oko, ati fun itọju awọn ile iwosan gbogbo ati ifẹsẹmulẹ ile ẹkọ ọfẹ ati bẹ ẹ bẹ ẹ lọ. Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun si ti ṣe alaye wọnyi fun awọn agbẹ, nwọn si gba a.

#### AWỌN AGBẸHIN BA ẸBỌ JẸ JALU U

EYITI awọn Ẹgbẹ Alakukọ iba fi ibaralẹ wo eto iru eyi, ki awọn le fi kọ ọgbọn, nṣe ni nwọn tako Ijọba pe nwọn nrẹ agbẹ jẹ ni, nwọn si sọ wipe bi o ba jẹ bẹ ẹ ni awọn yio rọ Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ki o kuku wa ra gbogbo koko Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ọgọjọ pọnun (£160) lati fi wa oju rere awọn agbẹ. nwọn ko mọ pe ọpọlọpọ awọn enia Naijiria ni o ti mọ awọn Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ni adabamalẹṣẹ.

(Wo oju ewe kẹtala)

# ALAPARA IBADAN

ALAPARA—Olotu, ẹ ku owurọ, a ko jire bi? Ṣe alafia ni gbogbo ile wa, iyawo ati awọn ọmọde?

OLOTU—A dupẹ o, alafia ni gbogbo ile wa o.

ALAPARA—Mo kan wa fi oju kan nyin pa a ni, mo fẹ lọ si idalẹ kan.

OLOTU—Nibo ni o fẹ ẹ lọ?

ALAPARA—Ni Ghana ni.

OLOTU—Kini o nlọ ṣe lọhun, o ki i sa a fẹ ẹ ku?

ALAPARA—Fifẹku bi bawo, ọrọ nyin ki i sa tete yemi.

OLOTU—Iyẹn ni pe gbogbo ọrọ ti mo ngma a ba ẹ sọ ki i tete ye o?



ALAPARA IBADAN

* * *

ALAPARA—Ẹ de o, Olotu, bi enia ko ba jẹun ka inu bi o ba wipe on yio duro ba nyin sọrọ de alaye porogodo nṣe ni ooyi yio gbe oluwarẹ.

OLOTU—Ewo ni ko nye ọ ninu ọrọ mi? Ṣebi iwọ ni o nsọrọ silẹ ti mo nda si i. Ẹtọ ni ki ẹni ti o sọrọ ma a gbọ esi, tabi ti nko ba nfun ọ lesi yio dun mọ ọ?

ALAPARA—Ki a ma a sọrọ, ki a si ma a ri esi ti o tọ ati eyiti o yẹ na ni mo fi nkọ ọgbọn lọdọ nyin, ti mo ba sọ pe ọrọ kan ko ye mi ninu ọrọ nyin mo fi purọ ni, ko ntete ye mi ni mo wi, lati fi ọrọ wa nyin ni ẹnu wo ni mo ṣe sọ bẹ ẹ. "Onisango ti o jo ti ko tapa, ni ara rẹ ni abuku wa" ki iṣe lara ṣango, eniti o ba sọ pe ọrọ nyin ko ye on, o nfi iwa ope han ni, ṣebi ẹnyin gan an ni a ba ma a pe ni alawiye

OLOTU—Mo gbọ eyiti o wi. Sọ fun mi, kini o nlọ ṣe ni Ghana?

ALAPARA—E jọwọ, nko le sọ fun nyin nitori ọrọ aṣiri ni.

OLOTU—Ọrọ aṣiri kan wa ti o ko le so fun mi lati ọjọ ti a ti jijọwa yi?

ALAPARA—Ẹ jọwọ ṣa! Ko si ọrọ aṣiri ti nkọ le sọ fun nyin, koda, bi emi pẹlu obinrin ba jijọ sun ti ilẹ ba mọ, mo le sọ fun nyin bi temi pẹlu obirin ti ṣe gbadun ara wa si ni gbogbo oru na. Ṣugbọn ọrọ aṣiri ti yio jade ninu beba fun gbogbo aiye ka, ni mo pe nko le sọ fun nyin. Ọrọ emi pẹlu nyin ti di ọrọ baba si ọmọ, bi mo ba tilẹ pe nko ni sọ ọrọ aṣiri fun nyin, nko ti nsọ ni ana ki o to di oni pe, "ọran ti a ni ki baba ma gbọ, baba ni yio pari rẹ."

Ibiti mo nlọ na, bi mo ba tun lu okun awọn ọmọ araiye onijibiti bi iru eyiti mo lu ni lu Saro, tani, ngo ko o wa ba, ẹnyin na ha kọ? tabi tani mo ko ti Sariyu Rọtikatika wa ba, ti o ba mi tu aṣiri irohin han gbogbo araiye? Nitorina ki ẹ ma ṣi mi gbọ, aṣiri ti yio yọ ninu beba fun gbogbo araiye gbọ ni mo pe nko fẹ sọ o.

OLOTU—Abata-pa Abata-pa, gbogbo iwọn-yẹn ti rekọja na o. Kini o nlọ ṣe ni Ghana?

ALAPARA—Ma a sọ ogere rẹ fun nyin ni bayi, ṣugbọn kẹtẹ-kẹtẹ idi rẹ ni yio jẹ ọrọ awa arawa ni mọba. "Nimọba o, nimọba awa ara wa ni mọba loni o". Mọ fẹ lọ ṣe iwadi iṣẹ-owo (trade) kan lọhun ni.

OLOTU—Owo ọti ni tabi ti obirin?

ALAPARA—Ẹ de o, Olotu, nigbati nko ṣe owo ọti, ti nko si nfi obirin ṣe iṣẹ ṣe, kini iba wa fa a ti ngo ti titori ti ọti ati ti obinrin lọ si Ghana? Ẹla ni ọrọ, ẹ jọwọ la a yẹ mi, a ko gbọdọ j'agbalagba ni iyan.

OLOTU—Ohun ti o mu mi bere bẹ ẹ ni pe, ọna kini, o fẹran ọti pupọ, bọya o si le ma a ri i ra ni ọpọku-ọyọku lati Oke Okun, bọya o si gburo pe awọn ọmọ Aganin i ma a ṣikọ okunrin pupọ ju ti ilẹ wa nihin lọ ni mo ṣe pe owo-ọti ni tabi ti obinrin?.

ALAPARA—O dara o, ki iṣe fun ti ọna mejeji ti ẹ darukọ yi, mo sa ti sọ fun nyin pe, ipinnu mi fun ọdun titun yi ni pe mo fi ọti silẹ, nko mu u mọ.

OLOTU—Ṣe o ṣe ipinnu ti ọbirin na pẹlu?

ALAPARA—Kini i ba fa a, iyẹn di ọjọ ti a ba ku, ki a to ye ara họ, a ki i dagba ẹyin adiẹ jijẹ ni ti ọro obinrin jẹ fun mi.

OLOTU—Njẹ ti o ba ri ọmọ ilu Ghana (Aganin) kan ti ifẹ rẹ ba fa si tirẹ, o ko ha ni i fa a loju mora bi yio ti ṣe ba ẹ wa mọ Naijiria?

ALAPARA—Nko le ba nyin jiyan iyẹn nitori iyawọ mi kekere ti lọ.

OLOTU—Iyawo rẹ agba nkọ?

ALAPARA Igbẹ-a-fẹwe! O ti lọ, ọna ti jin.

OLOTU—Ṣebi o sọ fun mi pe o ntọ ọmọ lọwọ?

ALAPARA—Pẹlu ọmọ na ni o fi ẹsẹ fẹ ẹ!

OLOTU—Kini fa a ti o fi lọ?

ALAPARA—Ẹ jọwọ fun mi laye ki ngma a lọ, bi mo ba pada de lati Ghana ma a wa sọ fun nyin.

OLOTU—Mọto ni o nwọ lọ si Oke Okun (Ghana) na ni tabi ọkọ oju-omi ni, tabi oko ofurufu?

ALAPARA—Oke ni ẹiyẹ nfọhun, kini iba fa a ti nko fi ni ma a fo, nigbati owo wa. Ma a fo lo ni. Owo wa, tabi ko sowo, allowo o, laifẹbirin!

OLOTU—O digbo-o-ṣe o. Ọkọ arefo o.




# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Ẹgbẹ Ọmọ Imala ṣe ajọdun alarinrin

IMALA, ABẸOKUTA.

ẸSE gbogbo awọn ọmọ "Ẹgbẹ Imala Youths Association" ti o wa ni Eko, Ibadan, Abẹokuta ati yika gbogbo awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ni o pe ṣọṣọ si ibi ipade ajọyọ ajọdun ti nwọn ṣe ni ilu yi ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrindilogun oṣu kejila ọdun ti o kọja yi. Ipade na si larinrin.

Ọgbẹni R. A. Adẹṣina, Alaga Ẹgbẹ na kan-saara si Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fun ọna mọto ọlọda ti nwọn ṣe lati Abẹokuta lọ si Aiyetoro ati Mẹkọ, ati ti eto ẹkọ ọfẹ pẹlu ile-iwosan fun awọn ọmọde O tun kesi Ijọba na fun iranlọwọ lati yọ ọda si titi ọna Igbo-ọra, Posu Ọfisi ati Ẹrọ-omi nitoripe aini awọn nkan wọnyi njẹ ara Imala ni iya. Alaga na tun ran Igbimọ Ijọba Ibilẹ Imala leti pe ki nwọn ma gbagbe lati gbẹ awọn kanga-omi kakiri awọn ileto ki nwọn si ṣe eto ẹkọ ọfẹ ile-iwe giga fun awọn ọmọ ile-iwe.

Ninu ipade yi ni Ọgbẹni M. O. Adegbiyi, ọkan ninu awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ Imala de pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti o ṣe aṣiwaju wọn wa. Awọn enia na ṣe ifilọ tẹduntẹdun pe awọn ọmọ Imala ti o wa lẹhin odi ko ran ilu lọwọ to nipa iṣẹ amojuto alafia ilu Imala, ṣugbọn awọn ero idalẹ na ni awọn gbojule fun iranlọwọ. Ọgbẹni T. A. Adekanbi, akọwe ẹgbẹ na si dahun si ifilọ wọn pe, ki iṣe wipe nwọn ko fẹ ṣe iranlọwọ, o si ṣe ileri pe awọn yio ṣe eto lati ṣe iranlọwọ na.

Ọgbẹni Oke I. A. Adelẹyẹ, Alaga Ipade na gba gbogbo ẹgbẹ ni imọran pe ki nwọn maṣe rẹhin ninu iṣẹ ilu wọn. Ọgbẹni Lawani Bamgboṣe si kin ọrọ rẹ lẹhin. Ki nwọn to mu ipade na wa si opin, nwọn yan awọn Alakoso Ẹgbẹ na fun ọdun yi (1961) awọn enia ti o wa si ipade na to ẹdẹgbẹta (500).

Aṣeyi-ṣamọdun o.

## Ọkunrin kan pe awọn alaṣẹ Ile Iwosan ni ẹjọ egbejila pọnun

IBADAN.

ỌKUNRIN kan ti nwa ọkọ ile iṣẹ ẹrọ omi ni Ibadan ti orukọ rẹ njẹ Dickson Igbokwe ti pe awọn alaṣẹ Ile-iwosan ile Ẹkọ-giga julọ (University College Hospital) Ibadan l'ẹjọ egbejila pọnun din mọkanlelọgbọn (£2,369) fun ofo ti nwọn ṣe on.

Ẹsun rẹ nipe dọkita kan ti o nṣiṣẹ nile Iwosan na ṣe iṣẹ ọbẹ fun iyawo on laigba aṣẹ tabi imọran on.

Idi pataki ti o fi pe ẹjọ yi ni pe, nipa aṣiṣe awọn alaṣẹ Ile-iwosan na ati ti olutọju alaisan kan ti orukọ rẹ njẹ Omidan Rosemary Morakinyọ, ọkan ninu awọn ti on pe lẹjọ pẹlu, ni ẹmi iyawo on fi bọ lojiji.

O si tun sọ niwaju adapọ pe onisowo ni iyawo on iṣe nigba aiye rẹ, atipe pọnun mẹta (£3) ni o fi nran on lọwọ loṣoṣu fun owo onjẹ. Lẹhin iku rẹ on gba olutọju fun awọn ọmọ ti o fi silẹ lọ. Pọnun mẹfa ni on si nsan fun olutọju awọn ọmọ na loṣoṣu.

Ọgbẹni Olu. Ayọọla ni agbẹjọro rẹ. Bi ẹjọ na ba si ti lọ si, awọn onkawe "Irohin Yoruba" yio ma a gbọ .


Nikehin wayi

abẹ infarungbọn to mu julọ




Ọbẹ Alafẹfẹ NACET Ọloni

Trade enquiries to: R. E. HARDING & CO. LTD · LAGOS · ABA · KANO



## BIBELI MIMỌ T'ỌRUN ỌWỌN IṢURA T'EMI



# "Tete kọ ṣe t'Ọlọrun na"

(Latı ọwọ Evangelist J. J. Akande I, Ogbomọshọ)

OPỌLỌPỌ enia ni ki i bikita lati tete kọ ṣe ifẹ Ọlọrun na, ṣugbọn nwọn a ma a kigbe nigbagbogbo pe ki Ọlọrun ṣe ifẹ ti nwọn fun wọn. Irun awọn enia bẹ ti Ọlọrun ko ba da wọn lohun, nwọn a bere si wa iranlọwọ lọ sọdọ eṣu, eṣu na a si fi igbadun ati ayọ igba diẹ tan wọn jẹ, nipa bẹ ẹ nwọn a di ọmọ eṣu ati ẹni egbe lọjọ ikẹhin.

Nigbati a ba nsọ fun ẹlomiran lati mura si isin ati iṣẹ Ọlọrun, a dahun wipe nigbati Ọlọrun ba gbọ adura on, ti ọkan on ba balẹ dada, nigbana ni on yio to le wa gbọ ti Ọlọrun.

Iru awọn enia ti o mu iru ọrọ aimokan bayi, nwọn ko mọ pe ọkan won ko le balẹ, bẹni nwọn ko si le ni itẹlorun lailai bi nwon ko ba gbọ ti Ọlọrun ṣaju gbogbo ife okan wọn.

**WOLI ELIJAH**

Nigbati iyan nla kan mu ni ilẹ awọn ọmọ Israeli nijosi, gẹgẹ bi a ti ri i ka ninu Awon Oba Kini, ori 17, ese 8-24, nigbati Woli Elijah de odọ obinrin opo ara Sarefati, ti o si bere onjẹ lọwo obinrin na, nigbana ni obinrin na dahun bayi pe, "Emi ko ni akara, sugbon ikunwo iyefun ati ororo die ninu kolobo, kiyesi i, emi nsa igi meji jo, ki emi ki o si pese re fun mi, ati fun omo mi, ki awa le jẹ e a si ku".

Orọ yi fihan wa pe onjẹ ikẹhin ti nwọn ni lati jẹ ti ko si si omiran fun won mo, afi ireti iku, iba onje na ni Elijah ba lọwọ won.

Sugbon Woli Elijah dahun wi fun obinrin na bayi pe, "Mase bẹru, lo ki o si se gẹgẹ bi o ti wi, ṣugbon ki o tete ko se akara kekere kan fun mi ninu re na, ki o si mu u fun mi wa, lehinna ki o ṣe tirẹ ati ti omo rẹ."

Bi o ti sọrọ to fun obinrin na lojo na, ko ṣe aigboran si aṣẹ Iranṣẹ Oluwa, sugbon o teteko se onje ti Elijah na, lẹhinna ni o sese fi iyẹfun diẹ toku se ti on ati ti ọmọ rẹ.

**ẸKỌ NLA**

Ni ikẹhin ọrọ na, ti obinrin na ninu ipọnju nla, ti o teteko ṣe ifẹ ti Ọlọrun na, ki o to ṣe ti ara re, nitorina ikoko iyẹfun na ko ṣofo, bẹni kolobo ororo na ko gbẹ, gẹgẹ bi ọrọ Oluwa ti o ti ipa Elijah sọ.

**Ki eyi jẹ ẹkọ fun gbogbo wa pe ere ati ibukun nla lo wa fun wa nipa teteko ṣe ifẹ Ọlọrun Ẹlẹda wa ṣaju gbogbo ẹdun ọkan wa.**

Nitorina bi o ti wu ki o ṣoro fun nyin to, ẹ maṣe jẹki o ṣoro fun nyin lati teteko ṣe ifẹ Ọlọrun lọna nyin gbogbo, ki ikoko iyẹfun ti nyin na le tete kun fun iyẹfun ati ki kolobo ororo nyin le kun fun ororo pẹlu.

Ẹniti o ba kọ tete mọ Ọlọrun ti o ba si jẹ olufokansin ki o to ṣẹṣẹ wa di olowo, iru enia bẹ ko le gbagbe Ọlọrun, ati pe yio ma a fi owo rẹ gbe iṣẹ Ọlọrun ga, yio si ma a fi se rere fun awọn enia.

**ALAIMỌKAN**

Ṣugbọn ẹniti ko mọ nkankan nipa titobi Ọlọrun, ti ko si mọ ilana isin Ọlọrun ki o to di olowo, iru awọn enia bẹ a ma a ṣoro sọ di onigbagbọ, nitoripe ede igberaga si enia ati si Ọlọrun ni yio ma a jade lẹnu rẹ pe, "Kini on yio ma a wa kiri, gbogbo ohun ti on nfẹ ni on ti ni, awọn ti nwọn sọ pe awọn nsin Ọlọrun na, ṣebi owo ni nwọn wa."

Ṣugbọn iru awọn enia alaimọ Ọlọrun bẹ ni Ọlọrun ma nsọ di ẹni iresilẹ patapata ni ikẹhin aiye won, ti igbẹhin ti wọn yio tile buru ju ti Nebukadnẹssari lo, ọba ti Ọlọrun sọ di eranko.

Fun anfani ara nyin, ẹ maṣe gbagbe ọrọ ti Ọlọrun sọ ninu Samuel Kini, ori 2, ẹsẹ 30, bayi pe, "Awọn ti o bu ọla fun Mi ni Emi o bu ọla fun, ati awọn ti ko ka Mi si li a o si ṣe alaikasi."

Nitorina ẹ fi ti Ọlọrun ṣiwaju gbogbo aniyan nyin.



Evangelist J. J. Akande


Ki ọpa-ẹhin le tọ-rọrọ ki tapa-titan si lagbara dada FUN ỌMỌ RẸ NI




OSTERMILK

Ile iṣẹ egbogi Glaxo Laboratories Ltd., Greenford, England ni ... ṣe e.

Awọn alagbata rẹ ni GLAXO-ALLENBURYS (NIGERIA) LTD. P.M.B. 2310. Lagos ati pẹlu ni ABA ati KANO

# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Awọn ọmọ Ijesha ṣe ajọdun

ZARIA.

LẸNULỌLỌYI ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Ijẹṣa ṣe ajọdun kini ni K2 T Wada, Zaria, ni ile alaga wọn. Ọgbẹni John Ofinran gbadura fun wọn ati gbogbo ara Naijiria ati fun igbega Naijiria. Lẹhinna ni nwọn bẹrẹsi jẹ nwọn si ngmu, nwọn si njo, nwọn nyọ titi nwọn fi tuka. Ajọdun na dun pupọ.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni M. Ariyọ, G. O. Fasugbẹ, Laṣebikan Oginn, Awẹ, Benjamin, Jacob Ofinran, E. O. Oginu J. T. Jẹgẹdẹ ati S. O. Awodiya, awọn Iyaafin J. Ladunni Ofinran, F. K Oginu, F Fasugbẹ ati J. Taiwo Ofinran.

## Awọn Ọmọ Ojoku ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ipade alarinrin



KONONGO-GHANA.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu kini ọdun yi ni awọn ṣe Ipade pataki na, ohun ti nwọn ṣe ipade na le lori ni pe, bi ilu wọn Ojoku yio ti ṣe ni ilọsiwaju ninu ibo ti nwọn yio di wọle Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa ninu ọdun yi.

Awọn ti o wa si ibi ipade na lati Kumasi ni awọn Ọgbẹni K. A. Bamidele ati S. Magaji, Adebayọ Alagbọn lati Akwatia, Alao Ọrẹ, S. A. Ajibaiye (aṣoju Iwe Irohin Yoruba) lati Mangoase, Salawu Giwa ati Suberu Adio ni o ṣe alaga ipade ọjọ na.

Ninu ipade na ni nwọn si ti yan Ọgbẹni S. A. Ajibaiye ati Garuba ni Eko lati lọ ba awọn Ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre ọmọ Ojoku ṣe ipade pataki ni Apapa Road Ebutemẹtta, awon enia ti o wa si ibi ipade na pọ pupọ.

Diẹ ti aye wa fun wa lati darukọ rẹ ninu iwe yi ni Ọgbẹni J. Kitibi (alaga) lati Eko, S. Agblara, S. Ajenipa, J. Lambẹ, S. Adisa, Lanbẹ (Agege) S. Babatunde, S. Adewuyi lati Mushin, J. Balogu,n Atanda lati Ojoku ,Hasani A. Balogun lati Ghana S. A. Ajibaiye ati Garuba Awẹda.

Aworan oke yi ni ti awọn ọmọ Ojoku ti nwọn wa si ipade na.


IRORA FẸRẸ JẸKI AWỌN APA KEJI NI IṢẸGUN!



1. Ijeṣa marun pere ni o ku ki nwon fun fere ikẹhin ni Joe seesi ti kokose ṣeṣe—o si ku bọlu-agbawọle kan ti nwon yio fi ṣegun!

2. Joe dubulẹ si ilẹ, o nke'rora. Lojiji, ore rẹ kan sare to o lọ. O ni "fi eyi pa a." o si gbe idẹ Mentholatum kan fun Joe.

3. Lẹsẹkẹsẹ ti o ti fi Mentholatum atura ati adẹra pa a. Joe bẹrẹsi gbadun. O ku iṣẹju kan ki nwọn fun fere ikẹhin.

4. Ah! Joe ti pada si aye awọn ti nwon lo si iwaju. o gba bolu ti nwọn gba si i si apakan lojiji—o si gba a wole! opelope iwosan Mentholatum. Joe ti gba ere-lie na la.

Bi o ba ni ẹsanra tabi irora tabi ẹfori fi Mentholatum atura ati adẹra pa ibẹ. Lẹsẹkẹsẹ a ti mu riro na kuro nibẹ. Wa a si bẹrẹsi gbadun aiye. Mentholatum darajulọ fun jẹdijẹdi, pẹlu —a tete mu itura wa! Bi i daju pe, Men-tholay-tum gan an ni, ti o wa ninu awọn agolo ati idẹ bi irufẹ iwọnyi ni ki o ra. Maṣe ra awọn adamọdi!



Awọn ti o nṣe e nikan ni

MENTHOLATUM CO. LTD.

(Est. 1889) Slough, England

MENTHOLATUM

IPARA TI O DARAJU




Aworan oke yi ni ti Ọlapeju Abakẹ Ajadi ti o ṣe orire jẹ ẹbun Kinni £3.000, nibi idije Orire Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun.


## IKỌ - FEE

### TI I DI ỌNA-ỌFUN ỌJỌ KANNA NI YIO DẸ

Maṣe jẹki ikọ-hihu, sinsin, didi ọna ofun ti ikọlu Ikọ olutu tabi ikọ-fee fi ọjọ kan tabi oru ọjọ kan ba orun tabi agbara ilera rẹ jẹ laiko dan MENDACO wo. Egbogi nla-nla yi ki iṣe ẹẹfin, abẹrẹ-gigun tabi fifọn, ṣugbọn ninu ẹjẹ ni o nṣiṣẹ, bayi ni o ti ṣe de inu ẹdọforo ati awọn iho-ọna-ọfun. Akolo rẹ yio bẹrẹ si ran ara lọwọ lẹsẹkẹsẹ ni ọna mẹta: Ekini yio se iranlọwọ a ti dẹ kẹlẹbẹ kiki ti o nfun ọ lọrun, yio si yọ o kuro. Ekeji. Bayi ni yio si fun ọ ni anfani mimi kalẹ ati pelu irọrun pelu orun asunwọra. Ẹkẹta. O nṣe iranlọwọ didẹ-ikọ, mimi tipatipa ati sisin. A ṣe ileri itẹlọrun ninu lilo rẹ tabi ki o gba owo rẹ pada. Ra MENDACO lọwọ apoogun loni.

## Da Ẹhin-didun ati Lakuregbe duro

Ijẹkulẹ ati imukumu, wahala, iṣẹ aṣeju, ọtutu igbagbogbo ati awọn kokoro-arun a ma a ko aarẹ ba awọn Eree (Kidneys) ati Ile-itọ a si so itọ di olomi aisan rukuruku, ki a ma a daji loru, ki itọ ma a jo ni nidi, ki ojugun ma a ro ni ki ara eni ma a gbọn, ki oju ma a su, ki kokosẹ wu tomutomu ati ki o darugbo ekun. Ran awọn Eree (Kidneys) rẹ lọwọ lati fi CYSTEX fọ ẹjẹ rẹ mọ. Akoko lo rẹ yio bẹrẹ si ran awọn Eree (Kidneys) rẹ lọwọ lati fọ omi aisan ati kokoro-arun kuro, lẹsẹkẹsẹ, wa a bẹrẹsi gbadun lakotun. A ṣe ileri pe a o da owo rẹ pada ti ko ba dara. CYSTEX ni lati fun ọ ni itẹlọrun patapata tabi ki o ma sanwo re ti ko ba dara. Ra CYSTEX lodo apoogun rẹ loni

Cystex fun awọn Eree (Kidneys) Lakuregbe ati Ile-itọ.

